TWENTIETH
EDITION 1952

*Printed by*

IFE-OLU PRINTING WORKS,
LAGOS, NIGERIA. 19 352, 5M

# AKIYESI

Ãnu ṣe mi lati ri pe lẹhin ti ogun ajakaiye nla yi pari tan ọ̀wọ́n ohun elo ati ọpọlọpọ ohun ti o yẹ ki a ni fun iṣẹ, alafia ati igbesi aiye enia ti a tun wa nri lẹhin ogun na buru ju ti arin ogun lọ, ọkan ninu awọn ohun ti o ṣọ̀wọ́n yi ni Iwe (*paper*) ti a fi ntẹ onirũrũ iwe kika ; bi o tilẹ jẹ pe a kò ri to bi a ti nfẹ ni igba ogun, a ri diẹ ti a fi ṣiṣẹ titi di ipari ogun ; ṣugbọn nisisiyi o ṣoro pupọ, a si ṣe wahala pupọ ki a to le ri eyiti a fi tẹ iwe yi, bẹni owo rẹ si wọn pupọ pẹlu.

Ni ọdun 1929 ni Ologbe ọrẹ mi A. K. Ajiṣafẹ ti tẹ iwe **AIYE AKAMARA** ati awọn iwe rẹ yoku bi **ENIA ṢORO, TAN' T'ỌLỌRUN**, &c., fun ẹkọ ati itọsọna awọn enia ninu iṣisẹ igbesi aiye wọn. Bi awọn iwe yi ti niye lori to, ti awọn enia si gbà wọn ati gẹgẹbi nwọn ti ndu wọn ra nibikibi to, li a nri ami anfani ti awọn iwe wọnyi nṣe fun gbogbo ẹniti o ba nka a.

Nitori idi eyi ni a ṣe kòkári lẹhin iku ọrẹ wa lati mã ṣe àtuntẹ̀ awọn iwe wọnyi, lati ri pe iṣẹ nla ti o ṣe silẹ yi kò parun lẹhin iku rẹ. Ṣugbọn o ṣe ni lãnu pe a kò ri iru iwe ti a ti fi ntẹ wọn ri, ti iba jẹ ki owo tita wọn lọ silẹ diẹ ; ifikun owo awọn oṣiṣẹ ati owo iwe ti a fi tẹ àtuntẹ̀ wọn titun iyi mu ki owo iwe kọ̀kan ki o ga pupọ, a si ni ireti pe igbadun ati anfani awọn iwe yi pọ jọjọ fun awọn ti o ba nka wọn tobẹ ti ẹnikẹni yio fi ri pe iye ti a nta wọn yi kere pupọ fun rira wọn ju anfani ati ẹkọ nlá-nlà ti o wa ninu wọn lọ.

Nitorina iba ti a ka ninu iwe itan oyinbo to, o si yẹ ki a mọ diẹ ninu itan ilẹ wa. Itan ilu wa kun fun ẹkọ. O si yẹ ki a kó wọn jọ sinu iwe gẹgẹ bi awọn oyinbo ti ṣe tiwọn ti o fi ni iyi bi ẹnipe bi o kò ba ka itan wọn, a kò le gbọn.

Gẹgẹbi awọn iwe yi ti ṣe anfani fun ọpọlọpọ awọn ẹniti o nka wọn to, bẹni a si ti nri iwe gba lati ọdọ ọpọlọpọ awọn ẹniti kò le ka a ni ede Yoruba pe wọn nfẹ ki a tẹ awọn iwe na ni ede oyinbo, ki wọn ba le ni ipin ninu anfani ti ẹkọ inu wọn fifun awọn ti o nka wọn, nitorina inu mi dun lati sọ fun awọn ọrẹ wa pe awọn gbedegbẹyọ ti bẹrẹ si ṣe itumọ abi iyipada yi ati pe a o gbiyanju lati tẹ wọn bi wọn ba ti pari iyipada wọn tan.

KASH AND KLARE BOOKSHOP,
Lagos, May 1, 1952.

I. W. OSHILAJA
*Managing Director*

## DIẸ NINU AWỌN IWE TI A NTA

Iṣipaya awọn iwe ti o yẹ ki a ni lọwọ, ki a si ka l'akaye fun igbesi ati ilo wa laiye. Awọn iwe yi kọ ni l'ẹkọ akọpe nipa ọna ti a fi le ni alafia ati itẹlọrun laiye. Bi enia ba ka wọn laka tan, ti o ba si tẹle ẹkọ inu wọn, kò si ifoiya fun u laiye, ọkan rẹ yio si balẹ nitori ti o mọ ọna ti on yio fi huwa lati tẹ Ọlọrun ati enia lọrun.

### IWE TAN T'ỌLỌRUN

Iwe yi kọ ni bi titobi ati ọla–nla Ọlọrun ti ri; ati pe, bi a ba fi otitọ gbẹkẹ wa le E, a ki yio dãmú, a ki yio ṣègbe, bẹni a ki yio pasan l'aiye. **1s. 6d.**

### IWE ENIA ṢORO

Iwe yi kọ ni pe ki a maṣe gbarale enia ninu ọna wọn gbogbo; ati bi ibayayò, iyẹnisi enia ati ileri rẹ ti jẹ omulẹmofo to. **1s. 3d.**

### IWE IGBADUN AIYE

Orukọ iwe yi ti fi itumọ rẹ han ni, eyiyi ni pe ẹkọ inu rẹ kọ ni pe, bi a ba fẹ gbadun aiye, ki a si jẹ igbadun yi pẹ, o yẹ ki a ka iwe yi, ki a si fiyesi ẹkọ inu rẹ lorõrí. **1s. 3d.**

### IWE AIYE AKAMARA

Iwe yi kọ ni l'ẹkọ pupọ nipa aiye, ìṣoro rẹ ati oniruru ẹkọ to yẹ ki enia mọ lati tọ iṣiṣẹ rẹ; ilosi ati ihuwa si ẹnikeji rẹ ni aiye aladun yi; o kọ ni li ọna ti a fi le tètè mọ ibiti kòtò ati gégélé wà laiye ki a ma ba ṣubu larin igbadun aiye wa. **1s. 6d.**

### IWE ORIN (ẸLẸKỌ AKỌPE) NI OHUN ILẸ WA FUN AWỌN ỌMỌ ILE IWE

A pin iwe yi si apa meji ki owo rẹ ma ba pọ̀ju fun awọn obi lati ra a fun awọn ọmọ wọn.

Awọn ọ̀rọ̀ inu iwe yi jẹ iṣipaya ọ̀rọ̀ ijinlẹ ẹkọ fun awọn ọmọde lati tọ wọn si ọna rere ni ihuwa ati igbesi aiye wọn A fi ohun orin aladun ilẹ wa kọ wọn, ki awọn ọmọde ma ba le gbagbe ọ̀rọ̀ wọn lati le ma ranti nigbati akanṣe ohun ti ẹkọ kọ̃kan ba kọ ni ba ṣẹlẹ. **6d.**

A O RI AWỌN IWE WỌNYI RA NI

**C.M.S. BOOKSHOP, LAGOS, NIGERIA**

ATI

NIBOMIRAN TI ILE-ITAWE WỌN WA GBOGBO.

# ITỌKASI

Oju Iwe

Itan Agíríàṣàṣà Tabi Yọyọ Lẹnu Araiye ... ... 7

Akalamagbò Ma Joju Ọrẹ ... ... ... ... 9

Ọrẹ Tòtọ Ati Ọrẹ Alabòsí ... ... ... ... 13

Ṣọreṣá ... ... ... ... ... ... ... 18

Fija F'Ọlọrun Ja ... ... ... ... ... 24

Ṣerarẹ ... ... ... ... ... ... ... 24

Ikuniya ... ... ... ... ... ... ... 27

Ikà Enia Kò Dun Mi ... ... ... ... ... 30

Suru Baba Iwa ... ... ... ... ... 33

Ariṣe Ati Atunmu ... ... ... ... ... 36

Ẹniti A Fẹ L'amọ̀ A Kò Mọ Ẹniti O Fẹ Ni ... ... 41